**Kere o!**

Aiyemoinba Almanak ti odun 1962 ti jade Tete wa ra tire Sile meji pere ni (2/) Ni eyo kan. Sile mejidilogun (18/) fun mejila.
Bere tabi ki o wa ra tire ni 86 Old Arolọya St. Lagos.

**IROHIN IMOLE**

MOTTO: IMOLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**NOW ON SALE**

Mu b a y e mi je Oluwa Calendar 1962 6d Copy 4/-6d Dozen.
OPE - OLUWA PRESS,
36, Abeokuta Street EBUTE — METTA LAGOS.

VOL. V No. 304 MONDAY OCTOBER 23 — OCTOBER 29 1961 KOBO MEJI (2d

# OBINRIN KAN FẸ YAGBẸ, DIPO IGBẸ ỌMỌ LO JADE

KANO- Ẹ BA MI RERIN! KE, KE, KE. ỌRỌ OKE YI LO FẸ MI NI EHIN SODE ON LO JẸKI NRIN ẸRIN KURUMỌ, NIGBATI AWỌN IJẸBU MEJI BA BARA WỌN JẸ OMITORO ỌRỌ NIGBA LAILAI, TI O BA PA WỌN LẸRIN, AWỌN ARA EKO A WIPE, ẸRIN OGODO NPA WỌN NI ẸRIN.

Bi irohin na ti mu ẹrin wa niyi, Obinrin Awure (Iyawo) kan, ti ko de ile ọkọ ri lo ni oyun, ko si gbagbọ pe oyun lo mbẹ ni inu on, Ṣugbọn oro o si arun.

Nigbati o di osu keje lo lo yagbẹ ninu ile igbẹ Iṣẹ kan na, ati Ibi ati Ire bọ silẹ. Obinrin na ko ri iru eleyi ri, lo ba gbe si nigbati o ngbọ igbe ọmọ o si sa lọ, obinrin miran ti o tun wọ ile gbẹ wa, lo n g b ọ igbe ọmọ lati inu pokiti wa, o yọju wo, o si ri pe ọmọ ni, o si rora fa a jade kuro ninu Pokiti, o si tẹ sile, o wa sare lọ rohin fun awọn Ọlọpa, awọn Ọlọpa gbe ọmọ na lọ si ile a l a i s a n, nwọn wa bẹrẹ si wa Iya to bi ọmọ na.

Nigbati awọn Ọlọpa ri iya ọmọ na, nwọn bere pe, nibo ni ọkọ rẹ wa? o si dahun wipe on ko iti ni ọkọ, nwọn t u n bere wipe ta lo fun loyun, o dahun wipe, nigbati nko iti ni ọkọ, ba wo ni ngo se loyun? Awọn Ọlọpa tun bere wipe, njẹ iwọ ha nsọ otitọ wipe iwọ ko mọ ọkunrin ri? o dahun pe ayafi nigba k a n ṣoṣo, igba kan ṣoṣo ko sa le mu enia loyun. Ni gbogbo awọn Ọlọpa ba bu si ẹrin. E o raiye lode bayi, ẹniti o nwa ọmọ loju mejeji ko ri, ẹ n i t i ko tilẹ wa rara lo nri ọmọ bi. Rekiya ni orukọ iya ọmọ na.

## Heparipa; Omo oro ni yi, oju mi ko ni ri oro omo

IBADAN:- Li ọ s ẹ to koja ni a se irohin nipa ọmọ binrin kan ti o njẹ Amina ti o loyun ọmọ abami kan nilu Bauchi ti o si jẹ wipe nwọn ni lati gbe lọ, si University Hospital ki o to le bi ọmọ na, nigbati o bi ọmọ abami na silẹ tan, wo mi na, Awe! ko se wo, ọrọ ati abami patapata ni ọmọ na.

Jẹki nse apejuwe iru ẹya ti awọn ọmọ na ya, nwọn jẹ Ibeji, nwọn ni ori meji lọtọtọ, nwọn ni ọwọ mejimeji lọtọtọ, nwọn ni igba aiya meji lọtọtọ, ṣugbọn a gbẹdu kan ṣoṣo ni wọn ni ti wọn n j ẹ u n si, ati ẹsẹ meji pere fun awọn mejeji. Amina pa itan ara rẹ fun awọn Oniwe Irohin, o wipe, ọmọ mẹjọ ni on bi ṣugbọn gbogbo wọn lo fẹrẹ ku tan, ọ k a n ṣoṣo ti o ku ninu awọn ọmọ rẹ ni eyiti o njẹ Garuba, lẹhin na ni on wa bi awọn Ibeji elemọ wọnyi.

Nigbati awọn Ayantọla, Oyanju ọrọ pọju ti awọn ero nrọ wa lati wa wo awọn ọmọ ọrọ na, wọn gbe wọn kuro lọ si ile iwosan ti o mbẹ lori oke J o s. Osita Miliki ati ọmu iya wọn ni wọn nmu. Iru ọ m ọ ọrọ bayi kan tun wa ni ilẹ Ilọrin, ṣugbọn Ijọba ko fẹ ki ẹnikan mọ, ṣugbọn wọn ku.

## Omo kan ti ko niya niyi



Ọmọ kekere ti a nwo yi, ni Iya rẹ bi tan ti o si gbe sọnu si oju agbara kan nilu Efọn ni waju ilu Oṣhogbo ẹniti o ri ọmọ na he, ni Wole-wole kan ti o njẹ Ọgbẹni W. Salawu, ni bẹrẹ ọdun ni January 1961.

Nwọn gbe lọ si Ile Alaisan ni Oṣhogbo fun itọju, ọmọ na si ti di Juku-juku, o dara o si lẹwa ṣugbọn a ko ri iya rẹ titi di bi a ti nṣọ yi.

Ijọba Iwọ Orun ke si Iya to bi ọmọ na, tabi awọn ara tabi awọn enia rẹ ki nwọn jade wa gba ọmọ wọn.

**Wanted**

2 Advance Apprentice Printers and 1 JournyMan. Apply to:-
MODUPE PRINTING PRESS
16, Bamgbose Street Lagos.

# Ọrọ Olotu

SI ỌGA ỌLỌPA

## Moto wiwo larin ona ko ye ki o ja si Owo

Lẹhin ti a ti gba O m i n i r a Ilẹ wa dolokiki, orisirisi ofin ni gbogbo enyin Oṣelu n m u wa ti gbogbo ifu si ma nsọrọ bi o ti dara tabi ko dara eyi ti ẹnyin na ba ri wipe o dara ẹ ma nfi k u n tabi ki ẹ yọ kuro ninu rẹ.

Ṣugbọn ninu gbogbo ofin na eyi ti o buru ju ti o si yẹ ki ẹnyin na mọdaju ni ti ofin wipe, bi mọto ba ṣeṣi ku ṣoju ọna ti yio di eyiti mọto awọn Munisipa yio wa wọ pẹlu Ponun marun ṣile marun, eyi jẹ ofin ti a ko rope o dara ti o si jẹ eyiti ẹnyin fi tubọ fun awọn Ọlọpa wa lọna iwa ọlẹ. Igbamiran wa ti o jẹ wipe epo mọto yio sa pa mọto lori, ti o si jẹ wipe o yẹ ki wọn duro fun igba diẹ, lẹhin igba diẹ yi ti wọn ba si dan wo yio tun bẹrẹ iṣẹ rẹ, ṣugbọn k a k a ki awọn a gba-lọwọ-meri yi se ajo na, fhalẹ ni wọn yio bẹresi ṣe, ki nwọn le dẹru ba awọn Oni mọto nitori a ti gba owo bọlẹ.

Ẹnyin ti ẹ joko ti ẹ ṣe Ofin wọnyi, igba pupọ ni mọto ti yin na ti ku si arin ọna, awa ṣebi enia bi tiwa na ni ẹniti o se mọto, nigbati a nsọrọ mọto, igba melo-melo ni ẹmi ti Ọlọrun wa da fun ra ara rẹ da ti o si sọ fun wa wipe igba ati aṣiko bayi awa tabi iwọ ,yio ṣe aisan tabi ti awa tabi iwọ yio ku?

Ti a ba ro eyi awa r o p e ko yẹ ki a ṣe ofin bayi bikoṣe ki a ran ara wa l ọ w ọ, awọn alawọ funfun ti nwọn tilẹ ti ya kuro ninu imọ ti wọn ti nba bọ lati ẹhin wa, nwọn ko fi irufẹ ofin bayi gbe wa de rara, ṣugbọn lẹhin ti o di tiwa tan, ni a ki fi ohunkohun ro ara wa wo ki a to se.

Bi awọn ọjọgbọn Mẹkaniki ti pọ to ni ọgba awọn Munisipa ti pọ sibẹsibẹ ojumọ k a n ko mọ ki Bọsi wọn ma ku sọna, bawo ni wọn ko ṣe nwọ awọn yen kiakia lọ si Ijọra tabi pẹlu o w o Ibọlẹ? Nigbamiran M ọ t o LF titun ti nwọn ṣẹṣẹ gbe jade lati inu ọgba ma nku sọna eyiti nwọn si ti nlo fun ọdun mẹwa sẹhin yio si ma kọja lẹgbẹ rẹ lai kọsẹ irufẹ alaye bayi ni o yẹ ki awọn ti o ṣe irufẹ ofin mọto gbigbe ti o ba ti ku sọna yi wo ki wọn to ṣofin na.

Ko si ẹniti yio fẹ jade nile ti yio ṣi ma gbadura tabi ti yio fẹ ki mọto oun ku sọna.

Igba miran wa ẹwẹ bi enia ti Ọlọrun da yio fi ile rẹ silẹ ti yio lọ si idalẹ ti yio si ku sọhun. O hale mọ ki o lọ bi? Rara!

Nitorina awa fẹ ki ẹ ba wa wo irufẹ ofin yi ki ẹ si ba wa se atunṣe rẹ. O yẹ ki ẹ se iranlọwọ lati wọ si ẹgbẹ kan fun atunṣe.

## Surulolere Anjorin Omo-oke Imale ni OMUPO

Awọn ti a daruko rẹ soke yi ṣe ipinnu lati ṣe ere nla aladun kan ti o miringiodin nIlu Eko ni Lagos Public School, 2, Eletu Iwashẹ Street ni dede agogo mẹjọ alẹ titi di meji oru. (8 p. m. - 2. a. m.)

Eniti yio ṣe ere na ni ọkunrin olokiki kan ti gbogbo aiye npe ni ALABI IKOTUN, ELERE ỌBA ILORIN.

Owo Iworan jẹ Ṣile marun, ati Ṣile mẹta. (5/- & 3/-) Awọn ti a ba fi iwe pe, a o gba owo iyi lọwọ wọn ni ẹnu ọna.

A le ri iwe iworan na ra lọdọ MALAM KADIRI IYANDA 36, Bankọlẹ Street, ati lọdọ Alega wa Alufa Idrisa 78 Ojuagbara Alley. Asi tun le ri Iwe iworan ra ni ẹnu ọna ile ere na.

Nwọn o ṣe ere na ni ọjọ 5th. oṣu November 1961. Iru ere ti Alabi Ikọtun na yio ṣe jẹ ijo agbe alarabara pẹlu ohun ti o dun, lati Ilọrin ni elere na ti n bọ wa

## Moto Taxi kan pa Obinrin Arugbo kan

Ijẹbu Ode:- A gbọ irohin wipe obinrin arugbo kan Ologorin ọdun kan, ni mọto Taxi kan pa ni apafọn ni Ijẹbu-Ode nigbati o mpada bọ lati ibiti o gbe ti lọ wo awọn enia rẹ. Orukọ Iya na ni Lẹse, awọn Ọlọpa ti ranṣẹ pe Dirẹba mọto na ki o wa wi tẹnu rẹ.

EJO BU OBINRIN KAN JẸ

Obinrin kan ti o le ni ọgọta ọdun ni a gbọ wipe ejo bujẹ n i g b a t i o lọ si oko iṣu, o si jẹ iya Adelebọ ti orukọ rẹ njẹ ọmọ Iyewulu bi o ti mbọ lati oko rẹ lo ṣe agbako ejo yi, ṣugbọn o pa ejo na ki on funra rẹ to ku.


## KERE O! AKIYESI PATAKI

Awa na le jẹri wipe ojulowo haunhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS, Awa na nlo ni ilu Goold Coast (A n k a r a) Ghana pẹlu, meji rẹ kosi ninu gbogbo orisirisi Egbogi kakiri Ilu Naijiria.




### Irohin kakiri Igoro Ilu Eko

Bena si n ẹwẹ ni Igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia, Ẹọmọde ti agba ni asiko yi ti wọn si nfi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn jẹ nipa ti Egbogi Jamani olokiki yi ti wọn npeni Leopills.

Imoran awọn Dọkita Oyinbo ti wọn ṣe Iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to, ti o jẹ oju lowo giriki ati atamatase fun iwosan JẸDIJẸDI bi o ti wu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹna ni awọn le tun le fi ọwọ sọya tabi ṣe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi aisan bi Akọ Inarun, Lakuragbe, Ẹjẹ didu lara, Arun Ẹdọki Iju Igbẹsise, tabi Aikori Igbọnsẹ dede, Inurirun nigbakugba Ara wiwo, Esanri, Ẹhin didun, Oju sisan tabi aiko riran kedere Kokoro buruku lara, O si inu Onigbameji, ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu "Wipe" wọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn ba nlo egbogi LEOPILLS nitoripe a si tun ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa siso di ọtun patapata.

SE IRANTI PE ALAFIA NI OGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU (POSTAGE 1/9d)

Egbogi Leopills:- Igo nla ṣile mẹfa pere ni.

Igo kekere Ṣile mẹta abọ pere ni.

Bere ojulowo Egbogi omiran fun orisirisi amodi ti o ba fẹ ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medice Stores**

**8, Palm Church Street, P. O. Box 333. Lagos Nigeria Phone: 22876.** ati pẹlu ni Ṣ ọ b u arabinrin Mrs C. O Babajide near Health Office Ibadan ati ni A b i m bọla Medicine Street B29 Okesha Street, Ilesha Bisale Medicine Stores, British & Foreigh Medicine (Dealer) S. W. 6/458 AGBOJO STREET, IBADAN, N.

AKIYESI:- Ki daju gbangba wipe Ṣọbu ti wọn nta lọ gbe ranṣẹ lọ ra, bi bẹkọ awọn ẹlomiran yio fi ERU lọ ta adamọdi tabi orisi omiran fun ọ o, maṣe gba rara

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Bi Ijaiye ti se di ti Yoruba

Lati Qwọ:- TIJANI ABANIKANDA
No. 65, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Ni igba lailai awọn Ọba Yoruba a ma gbe ilẹ Ọyọ, awọn Akọni a ma gbe ilu kan ti a npe ni Ikoyi. Onikoyi jẹ Ọba oko, o si saju ọpọ awọn Ọba miran. Ni wọn ọdun 1810 Adegun wa lori oye, eyini o jẹ Ọba Onikoyi. Nigbati o ṣe nwọn sigun si Ilọrin, a ma npe ogun yi ni Kanla, nwọn ranṣẹ pe Adegun Ọba pe, ki o wa ba wọn ni Ibudogun ko si le lọ, nitoripe wọn ti di rikisi si lati pa a, ogun yi buru pupọ, fun awọn Yoruba; ọpọlọpọ Balẹ lo ṣe gbe sibẹ.

Adegun Ọba gbe sibẹ, on ni Onakakanfo ti iṣe Balẹ Ogbomajugun ko bọ ninu ogun yi. Ojo Balẹ Ọsọokun pẹlu Balẹ Ọtẹfọn ṣegbe sibẹ pẹlu, nigbati awọn Yoruba iyoku bọ de ile, Idile Adegun ati awọn enia rẹ fẹ fi Ṣiyanbọla arẹmọ rẹ jọba, ni Lapami, nwọn si fi Ojo jẹ Ọba dipo, nwọn wipe ika enia ni Siyanbọla, bi o ba gun ori oye yio ba ilu jẹ, Awọn yi pọ to bẹ ti o fi di ija igboro, awọn enia Siyanbọla si ranṣẹ pe awọn Filani lati ran wọn lọwọ, nipa iran wọ yi Siyanbọla le awọn ọta rẹ kuro ni ilu, wọn sa wa si ilu kan ti a npe ni Ẹṣinẹlẹ si Ika-ọdan.

Lẹhin igbati onjẹ ilu yi ko to fun wọn mọ, wọn ranṣẹ lọ ira onjẹ lọwọ awọn Ẹgba ti ngbe ilu kan ti a npe ni Ijaye, Balẹ Ijaye li akoko yi a ma jẹ Mekaye Oyeniran, o kọ fun awọn Yoruba lati ra onjẹ tabi lati pi yẹ ni ilu ati oko ara Ijaye, nitori eyi Ikurunmi ati Dado, ti wọn jẹ Balogun Yoruba, bẹ ni Mekaye, wipe ogun ni o le awọn de igberiko rẹ, pe ki o fi yederu ki o ta onjẹ fun wọn, nigbati Onijaye kọ jalẹ, wọn fi ija lọ o, wọn si le kuro ni Ijaye.

Lati igba yi lọ ni Ijaye ti bọ si ọwọ Yoruba, Ikurunmi, Dado, ati awọn Akọni Yoruba iyoku, si fi Ijaye ṣe ile ni wọn A. D. 1815 ṣugbọn gbogbo ilu Ẹgba iyoku gba ọtẹ si awọn Isansa Yoruba, nitori ti Mekaye, bẹni ogun yi ran awọn Yoruba iyoku kakiri aiye, nwọn ja ilu Ẹgba iyoku logun, ni Ibadan. Nwọn si joko nibẹ, nwọn tun ko Ọwẹ, Ido, Sadika, Idere, Owu, Ikija, Igadẹ, nwọn gba gbogbo ilu wọn yi lọwọ Ẹgba, wọn si tẹ wọn do ni wọn A. D. 1818.

O to; iwọn ọdun mẹta lẹhin ogun wọnyi ni Labọside ati Mayẹ ara Ifẹ, sigun si Erunmu ṭọkan ninu Ẹgba iyoku, Ikurunmi ati awọn ara Ibadan ba; wọn lọ si ogun yi, nigbati yio lọ Ikurunmi fi Ojo sọ Ijaye, o si kilọ fun u pe bi awọn ayaba ba wa ojurere rẹ ki o maṣe fun wọn laye, nitori oni rikisi enia ni wọn.

---

## Omo egbe gbogbo Agbaiye niyi



Awọn mẹrin ti a nwo ninu aworan yi ni, ara awọn ọmọ ẹgbẹ gbogbo Agbaiye (Commonwealth) ti nwọn lọ se ipade nilu Oyinbo, orukọ wọn ni wọnyi:- Lati ọwọ osi Ọgbẹni R. A. Njoku ati Alaiyeluwa Ọba Samuel Akinsanya, awọn mejeji lati ilẹ Naijiria.

Ẹni kẹta ni Ọgbẹni L. H. E. Bury lati Ilu Australia, ati Ọgbẹni Mansinhji ara ilẹ India.

## Kini O mo Ni pa Ile Naijiria?

(1) Odun wo ni a bi Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ?
(2) Tani a bi ni ọdun 1904 ninu awọn Oṣelu Naijiria?
(3) Ilu wo ni wọn bi Ọlọla Nnamdi Asikuwe si?
(4) Darukọ awọn enia pataki nilẹ Naijiria to ja fun ominira wa, ṣugbọn ti ominira na ko ṣe oju wọn?
(5) Darukọ Ọlọla mẹrin ni Naijiria ti o mo pa oku lehin ti a gba Ominira?
(6) Ọjọ wo ni Ọgbeni J. E. Coker ti nse Baba Adajọ DR. G. B. Coker ku?
(7) Nigba wo ni a da Iwe Irohin Imọlẹ silẹ (b) Ọmọ Odun melo ni o di?
(8) Tani Ọmọ Ilẹ Naijiria ti o kọ jẹ oye, Gomina ti o si gba Ipo Ọyinbo, ni Naijiria?
(9) Tani Oludasilẹ Ẹgbẹ Dẹmọ?
(10) Ọdun wo ni wọn bi Baba Joaquim?
(11) Ilẹ Ẹko Giga wo ni Baba Joaquim lọ?
(12) Tani Baba Egbẹ Agba oselu Naijiria?
(13) Ilu wo ni a bi si?
(14) Tani o wa ṣe Asoju fun Ọba birin Ilẹ Gẹsi fun Ajọyọ Ominira wa l'ọdun 19/60?
(15) Kini wọn yio ti ma pe ile Alagbeka mẹdọgbọn ti wọn nko si Iwaju Ile-ẹkọ Giga Kings College (Race Course)
(16) Tani o fi Ipinlẹ Ile na le lẹ?
(17) Tani Olotu Ijọba ilu Saro (Sierra-Leone?)
(18) Iru ile wo ni wọn kọ si Erekusu Okun Apose li ọdun to kọja lasiko Ominira wa?
(19) Tani Olori Alatako ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria?
(20) Ile wo li ogun ju li Agbaye?
(21) Ilu bo ni o wa?
(22) Ọfọ tani o ṣe gbogbo enia Ilẹ Naijiria li Ọdun 19/58?

WO IDAHUN AWỌN IBERE WỌNYI NI OJU EWE KEJE

---

## Alo o? Alo!

Lati Ọwọ Gabriel Funṣhọ Afọlayan
Ọmọ Ẹgbẹ Imolẹ Aiye No 305 Lagos

(1) Bọmbọ-gudu meji fi ẹhin Igi - Ose
(2) Ọbarakata Imu Ẹsin ko ni Idin
(3) Ọpa tẹrẹ kan'lẹ o kan ọrun
(4) Alufa wa ni ile irungbọn rẹ yesita
(5) Ọlẹmoge a dara ma lojo
(6) Amu agbo dudu losi odo ode odi funfun (7) Eleti mẹrin jẹ oko babalua mitan

ITUMO

(1) Omu (2) Ọṣẹ dudu (3) Ojo (4) Agbado (5) Ẹnyin - Adiẹ (6) Ọṣẹ dudu (7) Odo

---

**Ema kawe Irohin Imole nigba gbogbo Enyin omo egbe Imole Aiye**





# IGBESI AIYE MI NINU IGBO AILOPIN (APA 6)

Lati Ọwọ:- Simeon Adegoke Fatoki

Awọn a b a m i ẹda wọnyi dupẹ lọwọ mi, nitoripe ọpọlọpọ igba ni asoju eṣu yi nma npa wọn jẹ, wọn si bẹrẹ si tu mi l ọ r ẹ orisirisi, nigbati mo simi diẹ, ti mo si jẹun tan, mo tun fi ina si ikoko taba mi, mo nlọ, mo si nyin Ọlọrun logo, ko pẹ pupọ nigbati mo kuro ni ibi ija yi tan ni ilẹ su, mo si wa abẹ itakun kan, mo fi ori pamọ sibẹ, mo si sun lọ.

O pẹ diẹ ki nto ji ni arọ ọjọ keji, orun si ti yọ dada, bi mo ti taji, mo wa onjẹ ti emi yio jẹ, mo jẹun, mo si fi ina si ikoko taba mi mo tun nlọ, ẹnu yio ya ẹnyin Onkawe yi pe, mo le mu ikoko taba pupọ, lotọ ni, emi ko le jẹun tan ki nma mu ikoko taba yi, nitoripe o ti di ohun ti o mọ mi lara patapata. Mo rin pẹ diẹ ni ọjọ yi, nigbati o si to nkan bi igbati a ma jẹun ọsan, ni mo ngbọ ariwo kan niwaju mi, aṣe ilu awọn Afọju ni mo nlọ kan yi, nko si rin jina pupọ nigbati mo kan ilu na. Mo de ẹnu odi mo si ba awọn Afọju meji kan, ti wọn gbe iwe kan lemi lọwọ, lati fi ọwọ si pe ti emi ti nko fọju ba ti le wọ ilu yi emi ko gbọdọ fi ilu na silẹ mọ, ati pe emi ni ngo jẹ Igbakeji Ọba, nitoripe Aditi ni Ọba wọn.

Nigbati mo wo iwe ti wọn gbe fun mi yi dada, mo sọ fun awọn asọna na pe, ki wọn jọwọ gba mi laye lati le ri Ọba wọn na. Inu wọn si d u n pupọ, wọn yan awọn Iransẹ meji tẹle mi.

Ohun ti o ya mi lẹnu nipe, nigbati awọn Iransẹ yi mu mi de arin ilu ti a si nlọ si ile Ọba, nipe lotọ ni awọn enia yi fọju, ṣugbọn wọn mọ ọna dada, wọn ko si sina rara titi wọn fi mu mi de ile Ọba. Wọn nya fun ara wọn lọna bi wọn ṣe nlọ, wọn si nki ara wọn pe, o da bọ o. Ẹnu ya mi pupọ, mo si ṣe i l e r i ni ọkan mi pe, emi yio mọ ohun ti o fa eyi nigbati mo ba de ile Ọba wọn.

Nigbati wọn mu mi de Afin Ọba, ẹnu ya mi pupọ nitoripe, bi Afin Ọba nla ni o ri, ti wọn si ṣe ni ọsọ gan, wọn gbin Ododo si ẹgbẹ oju ọna lọ, gbogbo rẹ si dabi ajule Ọrun.

## Obinrin yi luwe tan, o ngbadun orin



Ọmọde binrin ti a nwo ninu aworan yi njẹ igbadun orin lẹhin ti o ti luwẹ tan ninu odo, Ẹrọ ti o nkọrin na lo ti ha ṣokoto rẹ, o wa gbe igbọrọ rẹ si eti.

# Ajegboro dagba Nki Nyin o!

Mo ki gbogbo ẹnyin Ọnkawe Irohin Imọlẹ, papa ẹnyin ọmọ Ibilẹ Naijiria, ẹ ku ajọyọ ọdun kan Ominira wa, ẹ jẹki a dupẹ lọna esin Islam. Alhamidulilai. Ẹnyin Ẹlẹsin Kristẹni, ẹ jẹki a fi ogo f'Oluwa, Haleluya! ki gbogbo wa panupọ dupẹ fun Ọlọrun, A dupẹ f'Oluwa to ṣọ wa di ọjọ oni lati oṣu kewa ọdun tokọja ti a ti gba ominira, ti ko si ogun, ọtẹ, Ijagboro, ti a ko si lu ra wa pa, a dupẹ fun Eledumare, ọpọlọpọ rẹ Ọlọrun jẹ ko ba wa laiye pẹlu alafia, ṣe lomi idẹra fun wa, maṣe jẹki arun buruku kọlu wa. Gba wa lọwọ Iku ojiji.

Emi ọkunrin mẹta tun de! emi ọmọ abinu f'ọka pẹlu ọbẹ to dun jẹun yo, mo gbadun ajọdun Ominira wa emi pẹlu Adiya mi oreke lẹwa ẹlẹyin ju ẹgẹ.

HA! YOTỌMI LA WA BI ỌYAN MẸṢỌ,
OMINIRA WA, DI OHUN TI A KO LE GBA GBE

Ko ni dun to, bẹ si ni ko ni dara to ti emi ko ba sọrọ diẹ nipa Ominira wa yi. Kini itumọ ti o mo Ominira si? Itumọ ti emi le fun ri ipe:- Ifayabalẹ, Irẹpọ. Iṣọkan ati ododo, nitorina ni mo ṣe fẹ ba gbogbo ẹnyin enia ilẹ Naijiria sọrọ atata yi, ẹ jọwọ ẹ fi ara balẹ ka ọrọ na, ẹ ma sọ pe aroye mi npọju.

Awọn Oṣelu wa ni emi yio kọkọ ba sọrọ, mo bẹ gbogbo ẹnyin Alakoso wa ti kuku ida wa lọwọ rẹ loni Ẹ jẹki a ni irẹpọ nitori Irẹpọ ni agbara Orilẹ-Ede, ẹ jẹ ki a fi imọ ṣọkan, kiṣe pe ki a wa pọ nikan ka fi ifẹ pẹlu, ẹ jẹki a pa ọwọ pọ ka di ọkan ṣoṣo, ọpọ Irẹpọ ni mu ilu ni ilọsiwaju, ẹ jẹka fọtẹ silẹ, ọtẹ ki mu Ilu toro o ma nfa Orilẹ-Ede sẹhin ni, ẹ fi ọrọ ẹtan silẹ ki ẹ ma tan mẹkunu jẹ. Ẹ jẹki a wa pọ bi igbalẹ ti a di pa pọ.

O di ọwọ ẹnyin Oṣelu, ẹ jẹki a ṣiṣẹ tọkan-tọkan sin Orilẹ-Ede wa, ka tun bọ gbe ilẹ Naijiria ga.

Mo bẹ gbogbo ẹnyin enia Naijiria, ẹ jẹki a panupọ ba ara wa sọrọ otitọ, ka sun ka rori wo, ka fi Iwa Ika silẹ Ole, Igara, Imọtira nikan, Wobiya, Alọnilọwọgba, Ojukokoro, ati bẹbẹ lọ. Iru awọn iwa bayi ko gbe Ilu ga, wọn ma kere ilu wọn ko si njẹ ki ilu ni Ilọsiwaju nitorina o di ọwọ wa, ẹ jẹki a mura ki a sọ ilu wa di ilu Otitọ pẹlu Ilu ti awọn enia bọ bẹru ofin ti nwọn si pa ofin na mọ.

Mo bẹ ẹnyin Aṣoju Naijiria, ẹ ranti awa mẹkunnu ẹ mu iwa Imọtiraẹnikan kuro, ẹ fun ẹniti ko ti ri jẹ jẹ ẹ ranti pe igba ko lọ bi orere Aiye ko tọ bi ọpa ibọn toto o ṣe bi owe. Ẹ ṣanu mẹkunnu, gbogbo nkan ti ẹ ba ṣe silẹ loni bi ẹ ko ba jẹ ninu rẹ, ọmọ yin tabi ọkan ninu ẹjẹ yin mbọ wa jẹ nibẹ nitorina ẹ sọ otitọ..

Ẹ ma sọ Naijiria di ilu ti awọn Ilu okere yio ma poṣe le lori ẹsọ di Ilu ti wọn yio ma pọn ẹ jẹki a ni Irẹpọ, ka fi ọwọ wẹ ọwọ ko le mọ nitorina Irẹpọ lo mu ilọsiwaju fun Orilẹ-Ede.

O di ọwọ emi pẹlu rẹ bi Ilu Naijiria tiṣe yio da o.

Emi Ajẹgboro dagba pẹlu Iyawo mi, Adiya ki gbogbo enia Ilẹ Naijiria ku orire ajọdun ọdun kan Ominira Naijiria. Ẹmi gigun ati Alafia ara k'Ọlọrun fi ta gbogbo enia inu rẹ lọrẹ. Ka lo Ominira na pẹ.

# Moto Jomi-Joke ti o sese de!



Awọn Gẹsi gbe orişii mọto titun kan de, ti ko sibiti ko le lọ, ko si oke ti ko le gun, ko si odo ti ko le wẹ sọda. Moto na ni a nwo ninn aworan yi nigbati o de gongo ori oke, ati nigbati o nwẹ sọda ninu omi.


# Owo eni lafi tun iwa eni se

Bi ailowolọwọ ba nda ọ lamu, bi airọmọbi mba ọ lọkan jẹ, tabi airiṣẹṣe lo nyọ ọ lẹnu, tabi o tilẹ nṣiṣẹ na owo iṣọ na ko duro lọwọ rẹ. Tabi awọn Ọmọraiye ko jẹ ki o gbadun igbesi aiyẹ rẹ ni gbogbo ọna kona.

Ọkọ rere tabi aya rere lo njẹ ọ niya. Tabi amubọ ọkọ tabi ti aya, tabi ọja ti o nta ko lọ dede, tabi ohun miran lo mba ọ lọkan jẹ ni gbogbo ẹjọ.

Mọ daju wipe diẹdiẹ lo kọko bẹrẹ. Ki o si tun ọna rẹ ṣe. Kọwe pẹlu Şile Mẹwa abọ (10/6) pẹlu Sitampu oni tọrọ (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunṣe adanwo na lọdọ:-

AWORAWỌ
16, MOLẸYẸ STREET
P. O. BOX 166 YABA - NIGERIA



# MOGBAYI COUGH MIXTURE

Mogbayi Cough Mixture jẹ Ogun Ikọ pataki ti a ṣe ni aṣepe lati wo awọn Ikọ orişirişi san ni kiakia. O dara fun Ikọ agbalagba ati Ikọ ọmọde bẹni o si tun dara fun Ikọ ọmọ ọwọ pẹlu.

O dara pupọ ju gbogbo ogun Ikọ yoku lọ. O dara fun awọn arun Ikọ wọnyi, Ikọ ti o ma nha enia ni ohun, Ikọ ti o ma npọn enia loju, Ikọ ti ki jẹ ki enia sun dada, Ikọ ti o ma ndun enia lẹgbẹ, Ikọ ti o ma nta enia ni aya, Ikọ ti o ma nfa Ẹfọri, Ikọ ti o ma nfa arẹ ba ara, Ikọ ti o nmu ki enia ma pọ ẹjẹ, ati awọn Aisan miran ti wọn somọ Ikọ bi aiperi, oyi etc.

Mogbayi Cough Mixture yi dara pupọ fun ẹnyin ti Ikọ nyọ lẹnu, Ẹ ma ṣe ṣahun fun alafia ara yin, alafia ni opin ọrọ ijafara ni ewu pupọ, tete lọ ra Igo kan. Mogbayi Cough Mixture, yio wa ni ile itaja Egbogi ti o wa ni adugbo rẹ, Igo kan rẹ jẹ 2/6d' arapọ rẹ jẹ 24/-.)




LILO RE:-

Ọmọ oṣu mẹta—Idaji ṣibi tea kan ni wakati mẹtamẹta
Ọmọ oṣu mẹta si mejila:- Ṣibi tii kan nigba mẹta lojojumọ
Ọmọ ọdun kan si mẹfa:- Ṣibi tii meji nigba mẹta lojumọ
Agbalagba..............Ṣibi Imukọ kan nigba mẹta lojumọ

*Wholesale Distributors:-*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHER

6, Balogun Street West,
Lagos, Nigeria.
Phone 22515.

34, Docemo Street,
Lagos.
Phone 24247.

# Esi Oro Omo Aridegbaju

Lati Owo:- SISA ẸKUN TO JO JO KỌ.

Olotu/ Inu mi y/o dun ṣe ba le gba mi laye ninu Irohin Imole yio Olbyin momo lati fesi ọrọ Ọmọ Aridegtaju Oro to jade ninu iwe Irohin Imole ti ojọ Monday September 25 1961. Ibẹrẹ ọrọ mi, nigbawo ni Ọmọ Aridegbaju gboye Alufa to di eni ọwọ. Ẹnyin onkawe Irohin Imole e kiyesi igberaga ni ẹwaju iparun, ati pẹlu pe ọrọ ati iṣesi wọn ni yio fi wọn han. Ọmọ Aridegbaju tun nke si Anọbi wa Mohamed(Peace be on to Him) ati si Anọbi Ysa pe kio ti Olododo lẹhin, kio maṣe dojuti Olododo lailai, emi na ṣe amin nigba mọwa lẹna ọgọrun. Ṣugbọn mo tun nfẹ fi kun wipe ki awọn Anọbi Ọlọrun mejeji na to pe masai tuna aṣiri alabosi ati awọn ọdi Ilu ru enia moro wipe ọmọ Aridẹgbaju na yio ka mi ṣe anun eyi pẹlu. Ọmọ Aridẹgbaju tun nke si awọn Ọmọ Ilẹ Igbomina ati Offa, Ekiti ki wọn jinna sielo ti won ko ge lori, eno ni ejo ti a ko ge lori n nu ọrọ ti pe enia ti nṣe egbe oṣelu kan tẹlẹ, ti o si ni on ko ṣe mọ ti o si fararọ ẹgbẹ oṣelu miran ti o ro wipe o le ṣe on ati awọn enia on ni anfani ju ẹgbẹ ti on ti nṣe tẹlẹ lọ. Boya Ọmọ Aridegbaju kere ni koṣe mọ wipe enia le fi ẹgbẹ oṣelu kan silẹ kio si wo ẹgbẹ oṣelu miran. Fun apẹrẹ ẹgbẹ Aiakuko N. C. N. C. ta ni awọn wọnyi ti nṣe tẹlẹ Ogbeni D. K. Olumofin, Prince Adeleke Adedoyin, Otobo ati Oloye Agbaje ti Ibadan ati awọn miran bẹ bẹ lọ ti wọn si pada di opo mole ro ẹgbẹ Ọlọpẹ loni Ọmọ Aridẹgbaju adaluru pọ mọ sapa tun si awọn Ọmọ Ọtun Oro da ẹgbẹ ọdọ silẹ, kiṣe ẹgbẹ ọdọ ni wọn da silẹ nilu Oro rara, ṣugbọn ẹgbẹ N. P. C. ọdọ (N. P. C. Youth Wing) ni wọn da silẹ ti ẹgbẹ na si ngboro lojojumọ.

Ọmọ Aridẹgbaju tun tọka si pe ninu ẹgbẹ Igbomina Parapọ ni wọn ti kuro, kosi ẹnikẹni ti ko mọ eyi, ṣugbọn o dun mọ ni wipe ọmọ Aridẹgbaju ko ti Ibaje kan kan tọka si ti awọn Ilu Oro ṣe nigbati wọn wa ninu ẹgbẹ Igbomina Parapọ, nibo wa ni owe ti "Iya ajọ to nbi ọmọ rẹ bi Obinrin ti ẹiyẹ nyi lu ẹiyẹ ti jade".

Ọmọ Aridẹgbaju tun sọ wipe kini ṣe ti awọn ara ilu Oro ko fi wọ ẹgbẹ na ni ilu wọn. Eyi fi han gbangba wipe Ọmọ Aridẹgbaju yi ti de ajo o ti gbagbe ile ti papa o si ti de ile pẹ, bi ko ba ri bẹ, o ye ki o mọ wipe ọmọ Oro wa gidigidi ninu ẹgbẹ N. P. C. ti Ijoko rẹ wa ni Ajaṣẹpo. ti wọn ko si kere ninu Ipade ti wọn ṣe nibẹ.

IYOKU DI OSẸ TO MBỌ


BERE OJULOWO EGBGOGI AWỌN FARANSE TI A NPE NI:-

## "UROXAL"



Fun Itoju tabi fifọ Apo Ile Itọ Kidney - Bladder fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu Ẹhin didun eti ile tabi ito-jijo enia, ito riru, rukuruku Pipọn tabi rirun, lakuregbe, Ibara di wiwo, orunkun, ọwọ, ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju, aiko le gbe ara kọnkọn tabi kiakia, didaji loru nigbakugba, ati oriṣiriṣi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajebidan yi yio wo sen lara rẹ ni kia kia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ ko si ni Ilu Nayjria nitorina ṣora ki awọn eleru tabi awọn oni ọbirobi ma ta oriṣi omiran ti ko ni lari fun ọ, maṣe gba rara o!

Owo rẹ jẹ Sile Mefa abọ 6/ 6d owo ọkọ sile meji abọ (2/ 6d)

Bere Egbogi yi ni Ṣọbu awọn Saro ti wọn npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**


## Akiyesi Pataki

Ẹ wa wo ere Ijo aladun ti Ẹgbẹ (The Oke-Ọla Friendly Society) pe gbogbo yin sibi ere ijo aladun ti a o ṣe ni Forester's Hall, Lagos, ni ọjọ Jimoh tiṣe 27/10/61. Ẹ le ri Tikiti ra ni ile iṣẹ Irohin Imọlẹ, (16, Bamgboṣe Street Lagos), sile mẹta pere (3/- Flat.) M u s i c by: Empire Raythm Orchestra.

# Asoju ile Rhodesia gbalejo



Awọn ti a nwo ninu iwe yi larin awọn meji ti o jẹ oyinbo asoju ilẹ Rhodesia ni nigbati awọn Agbẹ ilẹ Nyasaland lọ bẹ ilẹ iṣẹ rẹ wo. Orukọ wọn ni yi lati ọtun si osi. W. H. Kona, O l o r i awọn agbẹ na J. Jacha, agbẹ, A. K. Walubita, ati Y. K. Kapọnda.


## PAYAL (IPARA)

Ati awọn oriṣiriṣi omiran irufẹ rẹ jẹ ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidigidi fun "Ipara" ti awọn ailera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu ni ode ara. Ara, ọwọ tabi ẹsẹ hihun tabi yiyun nigbakugba Alefọ. E g b o Ẹsẹ oriṣiriṣi tabi ti ojọ rẹ ti pẹ bi adajinọ Egbo, Ekuṣẹ tabi Lapalapa, Ela, Ara sisan, Akọ Inarun, Sobiya Afọju ati oriṣiriṣi arun "ARA" miran gbogbo.





Gbiyanju lati dan egbogi k o k o r o titun ti awọn ara Ilu Tatanbulu ṣe ti wọn npe ni "PAYAL" wo larin ijọ mẹta iwọ na yio ma rohin rẹ fun aw ọ n elomiran pẹlu. Egbogi ipara yi ki ṣe awọn robirobi ti wọn nta kakiri ilu ni owo poku. Ojulowo egbogi arun ara haunhaun ti ko si ṣiṣe iyẹ meji ninu rẹ eleyi si yatọ patapata si awọn egẹrẹmiti adimọwọ ti wọn nta kakiri Igboro ati ni agbereko gbogbo pẹlu. Oriṣi meji rẹ lowa, Kekere ati Nla.

Bere Egbogi Ajẹbina PAYAL yi ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.
ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN

# Kini o mo nipa Ile Naijiria?

EYI NI IDAHUN AWỌN IBERE TO WA LOJU EWE KẸTA.

(1) March 1909 (2) Dr. Nnamdi Azikiwe
(3) Zunguru ni Ipinlẹ Ariwa. (4) Herbert Maculay, Bode Thomas, Adelabu. (5) Ọlọla Algernon Brown ti nse Adajọ agba ni ipinlẹ Ariwa, Ernest IKoli, Isaac-Thomas, Fẹmi Pearse
(6) June 27, 1961 (7) Lodun 1957, Ọmọ Ọdun mẹrin
(8) Ọlọla Adesọji Aderẹmi Ọni Ile Ifẹ.
(9) Herbert Maculay, (10) Lọdun 1884
(11) St. Gregory's Grammar School (12) Dennis-Osadebay. (13) Ni Asaba lagbegbe ilu Benin,
(14) Ọmọ ọba Alexandra. (15) Ile Ominira (Indepence House) (16) Ọmọ Ọba Alexandra ti Ilu Kent. (17) Ọlọla Milton Magai. (18) Ile eyẹ Ifihan Naijiria. (19) Ọlọla Fani Kayọde (20) Sky Scrapper. (21) Ilu America. (22) Ọfọ Adegoke Adelabu.

BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TONIKI TITUN TI O ṢẸṢẸ DE TI WỌN NPE NI:-

"DYNAMI REN" TONIKI

EGBOGI AJẸBIDAN FUN AGBALAGBA OKUNKIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awọn Jamani ti nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ. Lẹhin igbana a ko ri irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju bẹ yẹn mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ranṣẹ si awọn Ogbologbo Dokita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye. Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ atipe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu. Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Oni-bara wa mọ daju wipe kosi aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Ẹgbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi kọ. Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko ba le jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de okọn lọsan tabi loru, bi awọn "Iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara to E·emi (breath) inu ko ba gunle da radara to nitoripe arẹ tabi wahala ṣiṣe ko "NJẸ" fun awọn ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun lọ si oke de adọrin tabi jube lọ mọ daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di Ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara re ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gba kọnkọn nigba kugba "Arẹ" nigbakugba yio salọ patapata pẹlu.
Igbadun ati Alafia yio de si ọ.
Bere egbogi na ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS PHONE: 20278.

ADEDUN CHEMIST
4, WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

## ORO PATAKI FUN AWỌN OBINRIN

Lati Ọwọ:- Iyalin Alakẹ

### Ona wo ni mo le gbe gba?

Alakẹ/ Mo ni ọrẹ obinrin kan ti o nfe mi jọjọ, nigbogbo igba ti o ba da aṣọ titun yio da fila fun mi ninu rẹ, bi o ba gbọ pe mo ni owo lati lo, yio ṣe iranlọwọ rẹ fun mi. Mo ba sọrọ pe ki o fẹ mi, o kọ. Bi mo ba fun ni owo, tabi nkan miran yio kọ, mo tun ba sọrọ ki o jẹki a ṣe ọmọloju lọ si Oju-koto, o tun kọ. Njẹ iwọ Alakẹ, Kini mo tun leṣe fun ti o le tẹlọrun.

EKO D. A. ATANDA

Idahun:- Atanda! ranti pe, gbogbo nkan ti Ọlọrun ba fi alubarika si ni yio jẹ ṣiṣe, maṣe titori rẹ ba a ja ohun gbogbo ti Ọlọrun ba ṣe laiye yi, rere ni igbẹhin rẹ nja si, Bi o ba jẹ wipe aṣẹ Ọlọrun wa ninu ki ẹ fẹ ara nyin, dandan ẹ o fẹ ara nyin na ni.

Read The IROHIN IMOLẸ every week. It is a Yoruba Weekly Paper that will provide you with more News more Pictures and more Fun. It will enlighten, entertain and inform you. Always read:-

"Irohin Imole"

The most exciting controversial Yoruba weekly Paper



## Nigerian Ports Authority

**Vacancies - Electrical Engineer and Foremen (Electrical)**

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the following posts in the Engineering Department of the Authority.

ELECTRICAL ENGINEER.

QUALIFICATION:

Candidates should possess a degree, or as minimum, Higher National Certificate, in heavy electrical engineering and should be a Graduate or Associate Member of the Institution of Electrical Engineers. Candidates must have served a full term of apprenticeship with recognised electrical organisation and have had subsequently at least two years experience on one or more of the following:-

H. V. and M. V. distribution systems
A. C. and D. C. motors
Ships Electrical systems
Electric Cranes.

A working knowledge of radio telecommunication system would also be an advantage.

DUTIES:

The successful candidates will responsible to the Senior Electrical Engineer for assisting in the design of electrical extensions and also for the general operation and maintenance of electrical equipment in the various Port areas.

SALARY:

Salary Scale 5: £1, 350 x 56 - £1; 686 per annum plus Overseas pay where applicable.

FOREMEN (ELECTRICAL):

QUALIFICATION:

Applicants should have considerable previous experience in the control of staff and should have extensive practical knowledge in at least one of the following spheres. Theoretical knowledge or the subject will also be an advantage:-

Ships electrical systems
Factory distribution and wiring
A. C. and D. C. Machines
Domestic Electrical Equipment.

SALARY:

Scale 7: £902 x 56 - £1, 462 per annum.

METHOD OF APPLICATION:

Application forms are obtainable from the Personnel Manager, Nigerian Ports Authority, Apapa Dockyard, and should be completed and return so as to reach him not later than 26th November, 1961. Candidates in the service of the Government or a Corporation must submit their applications through their Heads of Departments who will forward them to the Personnel Manager along with confidential reports. Persons without requisite qualification and experience need not apply.

*BAYO KEHINDE*
*Secretary to the Authority*

N. P. A. Notice No. 637.

20th October, 1961.

## Akiyesi Pataki

**Sengovan Tablets! Sengovan Tablets!!**

SENGOVAN Tablets: Jẹ ajidewe fun awọn agbalagba ati Ilera gẹgẹbi ọmọkunrin.

SENGOVAN: Jẹ ọkan pataki ti a ṣe iwadi ni ilu Okere ni ile Jamani lowọ ọkan ninu awọn Ọjọgbọn Onisegun Aremọ ti ilu Western Germany. Fun are ara ẹniti ọjọ ori rẹ to Ogoji si Ọgọrin ọdun (40: 80. years.)

SENGOVAN:- Jẹ ogun ti o ti wa lọjọ pipẹ fun anfani awọn Agbalagba Ilu Jamani, ki a to ṣe amuwa rẹ si ilu Naijiria. Ajẹbidan ni ogun yi Irohin ko to afojuba.

Bere, A o ri lowọ awọn Onisegun (Doctors) Naijiria tabi lowọ Alagba Messers HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES. 26, BISHOP STREET. LAGOS PHONE: 23745. DIRECTION: 1 to 2 Pills is sufficient for your constitution, if so do not take more pills at one time. SENGOVAN IS FOR YOU.

## Egbe Eka Olomi (N. P. C.) ti Ilu Omupo.

(LAGOS BRANCH)

Awa Ẹgbẹ ti orukọ wa, wa, loke iwe yi fi tayọtayọ pe ẹnikẹni lati wa wo ere aladun ti a o se ni Ilu Eko, ni ile Ẹkọ ti wọn npe ni Lagos Pulbic School, 2, Eletu Iwaṣẹ Street, Ẹbu Ọwa Lagos ni ọjọ Saturday ti se ọjọ Kerin Osu to mbọ 4/11/61, ere yi na si tun jẹ ti ajọdun ọdun kan Ominira ilẹ Naijiria ere na yio bẹrẹ lati agogo mejọ alẹ titi di mejila oru.

Ẹniti yio se ere na ni Olokiki, alu ilu bi alara, Ajadi ti ilu Ilọrin, elere alapala Ale ri iwe iworan na ni ọdọ Ọgbẹni Kadi Wadawu ni NO 68, Oluwọle Street Lagos ati loju ọna ibiti a o gbe ṣe ere na.

Gbogbo awọn Asoju (Ministers) Olomi (N. P. C.) ni yio pese sibi ere na, ati gbogbo awọn enia patakipataki ninu Ẹgbẹ Olomi ti ilẹ Igbomina ati ti Ilorin, Ọifa ati ati Ekiti ni yio pese sibe.

Nitorina mase jeki ere na fọ ọ.

**GBANGBA DEKUN!! KEDERE BEWO!!!**




OLUBORI EGBOGI "IKỌ'

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu fun nkọn bi ọdun kan tabi jubẹ lọ, awọn egbogi rọbirọbi ko le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ ṣe Ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara Ilu Faranse ti wọn npe ni 'PORAL" ojulowo haunhaun, atamatase egbogi fun Ikọ bere, Ikọ tutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaiya, Ikọ tile, Ikọ" ti ọ ma mu enia tu kẹlẹbe nigbakugba lati isu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ma nmu enia ru pẹlu. Bi o ba dan Igo kan egbogi PORAL yi wo, Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia, Igbaaiya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro, "IKỌ" rẹ yio si san patapata, iwọ yio ma jẹun daradara iwọ o si sun fọnfọn pẹlu Alafia de.

Bere egbogi yi ati awọn orisirisi Egbogi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.
ADEBỌGUN PATENT MEDICINE STORES
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN

Printed and Published by DUPE PRINTING PRESS
16, Bamgbose Street Lagos, Phone 21985 Olotu. E. A. Adeniji
51, Fẹinoso Street Surulere YABA.
FUN OWO IROHIN IMỌLẸ ỌDUN KAN
EKO:- Ṣile Mẹjọ ati Kọbọ Mẹjọ (8/8d)
Ilu miran ni Naijiria ati Oke Okun:-
Ṣile mejila ati Kọbọ Mẹfa (12/6d)